# ÒFIN MEMORIAL HERMANN HEALTH SYSTEM

**ÀKỌLÉ ÒFIN:** Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó

**DÉÈTÌ ÀTẸ̀JÁDE:** 12/19/2017
**Ẹ̀YÀ:** 4

---

## ÈRÈDÍ ÒFIN:

Memorial Hermann Health System ("MHHS") ń ṣiṣẹ́ Kóòdù Àgbàwọlé Abẹ́lé òfin 501(c)(3) àwọn ilé-ìwòsàn tí ń pèsè àwọn ìní ìtọ́jú ìlera ti Harris, Montgomery, Fort Bend àti àwọn àyíká orílẹ̀-èdè. MHHS jọ̀wọ́ ara rẹ̀ láti pèsè àwọn ànfàní agbègbè ní ọ̀nà ìrànlọ́wọ́ owó fún àwọn ènìyàn tí kò ní ìdójútòfò tàbí tí kò kún ojú ìwọ̀n tó, láìsí ẹlẹ́yàmẹ̀yà, tó nílò àwọn iṣẹ́ tó ṣe pàtàkì fún ìlera tàbí ti pàjáwìrì tí kò sì níṣe pẹ̀lú agbára aláìsàn láti sanwó.

Èrèdí Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó yìí ("FAP") ni láti pèsè ìlànà kkan fún dídámọ̀ àti pípèsè ìrànlọ́wọ́ owó fún àwọn tí MHHS ń sìn láàrín àdúgbò.

## ÌWÒYE:

FAP yìí kan gbogbo àwọn ohun èlò ilé-ìwòsàn tí ìjọba ìpínlẹ̀ fún ní àṣẹ nípasẹ̀ òfin 501(c)(3) àwọn ilé-ìwòsàn MHHS, èyí tó kan:

Memorial Hermann Greater Heights Hospital
Memorial Hermann Katy Hospital
Memorial Hermann Memorial City Medical Center
Memorial Hermann – Texas Medical Center

- Memorial Hermann Cypress Hospital
- Memorial Hermann Orthopedic and Spine Hospital

Memorial Hermann Northeast Hospital
Memorial Hermann Rehabilitation Hospital Katy, L.L.C.
Memorial Hermann Southeast Hospital

- Memorial Hermann Pearland Hospital

Memorial Hermann Southwest Hospital
Memorial Hermann Sugar Land Hospital
Memorial Hermann The Woodlands Medical Center
TIRR Memorial Hermann

MHHS ń ṣiṣẹ́ àwọn gbọ̀ngán àwòrán aláìsan òde, ògùn òyìnbó eré ìdárayá àti àwọn gbọ̀ngán ibi ìtọ́jú, àti àwọn gbọ̀ngán pajáwìrì bíi èyí tó dá lórí olùpèsè, àwọn ẹ̀ka iṣẹ́

aláìsan ode ti àwọn ilé-ìwòsàn tí a dárúkọ lókè, wọ́n sì wà lábẹ́ FAP yìí.

MHHS tún ṣe yàrá àyẹ̀wò aláìsàn òde èyí tó wà lábẹ́ FAP yìí.

**GBÓLÓHÙN ÒFIN:**

1. Ìṣedédé pẹ̀lú àwọn ohun iyì MHHS ti ààánú àti ìsìnrú, ó jẹ́ òfin MHHS láti pèsè Ìrànlọ́wọ́ Owó fún àwọn aláìsàn tí kò ní. Síwájú síi, èrèdí FAP yìí ni láti pèsè àtúpalẹ̀ iṣẹ́ lábẹ́ èyítí a ó fún àwọn aláìsàn ní Ìrànlọ́wọ́ Owó fún ìtọ́jú tó ṣe pàtàkì fún ìlera àti pàjáwìrì èyítí MHHS ń pèsè.

2. FAP yìí n dá ìlànà ìwé ìbèrè àti àmúyẹ pàtó kan mọ̀ lábẹ́ èyítí MHHS yóò fa Ìrànlọ́wọ́ Owó gùn sí àwọn ènìyàn tí kò le sanwó tán fún àwọn iṣẹ́ tí a pèsè. Ṣàkíyèsí pé àwọn ènìyàn kan Lẹ́tọ̀ọ́ Bí a ti rò láti gba àwọn iṣẹ́ lọ́fẹ̀ẹ́ (wo Ìlànà Abala 4).

3. FAP yìí kan gbogbo ìtọ́jú pàtàkì ti ìlera tàbí pàjáwìrì èyítí ilé-ìwòsàn MHHS ń pèsè. FAP yìí kò nípa lórí àwọn olùpèsè àwọn iṣẹ́ ìlera lóde ilé-iwòsàn kò sì kan àwọn iṣẹ́ dókítà. O le rí àkójọ àwọn olùpèse tí ń ṣe iṣẹ́ pàjáwìrì tàbí ìtọ́jú pàtakì ti ìlera míràn nínú ohun èlò ilé-ìwòsaǹ èyítí àwọn iṣẹ́ rẹ̀ wà lábẹ́ ara FAP yìí, àti akójọ àwọn olùpèsè èyítí àwọn iṣẹ́ rẹ̀ kò sí lábẹ́ ara FAP yìí lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa ní: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/. Àwọn ẹ̀dà pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn agbègbè ìforúkọsílẹ̀ ilé-ìwòsàn. Àwọn ẹ̀dà pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ nípasẹ̀ lẹ́tà tabi nípa pípe (713) 338-5502 or 1-800-526-2121, Àṣàyàn 5.

4. FAP náà ṣàlàyé àmúyẹ tí a lò nípasẹ̀ MHHS láti ṣírò iye ẹ̀dínwó Ìrànlọ́wọ́ Owó, tó bá wà, àwọn ìgbésẹ̀ tí MHHS yóò gbé láti polongo FAP yìí láàrín agbègbè tí MHHS ń sìn, ìlànà iṣẹ́ tí MHHS ń lò láti pinnu àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti ìlànà ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. Àwọn ìgbésẹ̀ tí MHHS le gbé tó bá ṣẹlẹ̀ pé ẹnìkan kò sanwó ni a ṣàlàyé nínú òfin míràn, MHHS Òfin Ìdíyelé àti Gbígbà. Òfin yìí ni a le gbàsílẹ̀ lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHHS ní: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/, tàbí ẹ̀dà pépà lọ̀fẹ́ wà nílẹ̀ ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi agbègbè ìforúkọsílẹ̀ ilé-ìwòsàn. Àwọn ẹ̀dà pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ nípasẹ̀ lẹ́tà tabi nípa pípe (713) 338-5502 tàbí 1-800-5262121, Àṣàyàn 5.

5. Láti yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó, àwọn aláìsàn gbọ́dọ̀ parí ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó kí wọ́n sì fàá kalẹ̀ (fún àwọn aláìsàn tí a Rò wípé Kò Yẹ) pẹ̀lú àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tí a bèrè fún. Àwọn ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó yẹ láì kọjá ọjọ́ 240 lẹ́yìn déètì owó àkọsílẹ̀ ìdíyelé àkọ́kọ́ tí a firánṣẹ́ fún èyítí o ń bèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. A le fún ọ ní àwọn yíyáfì kan bí a ti ṣàlàyé nínú Ìlànà Abala 9. Kò sí ohunkóhun tó wà nínú FAP tó ṣe pàtàkì ju àwọn òfin àti ìṣedédé ti ìjọba abẹ́lé, ìpínlẹ̀ tàbí àpapọ̀ lọ́wọ́ èyítí a ṣe lónìí tàbí tí a ó ṣe ní ọjọ́ iwájú.

6. Èyíkéyìí owó tí aláìsàn náà bá san ní àpọ̀jù lẹ́yìn ẹ̀dínwó ìrànlọ́wọ́ owó tí a lò ni a

ó dápadà fún gbogbo àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìtọ́jú.

7. Àṣẹ olúborí láti pinnu bóyá MHHS ti gbé ìgbésẹ̀ tó dára láti pinnu àmúyẹ FAP wà pẹ̀lú Ibi-iṣẹ́ Ìṣòwò Aláìsàn MHHS. FAP yìí ni a ṣe láti ṣe ànfàní fún agbègbè MHHS tó ṣe déédé pẹ̀lú àwọn iyì rẹ̀ ti àánú àti ìsìnrú. Wíwàníllẹ̀ FAP yií kìíṣe ìfúnni ní Ìrànlọ́wọ́ Owó fún èyíkéyìí aláìsàn kan ní pàtó kò sì ṣẹ̀dá àwọn ẹ̀tọ́ àdéhùn tàbí ojúṣe kankan. FAP yìí ni MHHS le mú dójú òṣùwọ̀n ní ọjọ́ iwájú kí Ìgbìmọ̀ Aláṣẹ tàbí aṣojú wọn si fọwọ́síi ní èrò tirẹ̀.

8. Àwọn òfin àti ìlànà tí a sọ wọ̀nyí ni ó gbọ́dọ̀ bá ìṣedédé ti ìlú Texas mu àti Òfin 501(r) ti Kóòdù Owó Agbawọlé Abẹ́lé, àti ìlànà tójọra.

**<u>ÀWỌN KÓKÓ ỌRỌ̀ ÀTI ÌTUMỌ̀:</u>**

1. *Ìwé Ìbèrè*: Túmọ̀ sí ìwé ìbèrè kan fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ní aláìsàn kan gbọ́dọ̀ fọwọ́sí.

2. *Àkókò Ìwé Ìbèrè:* Ní Àkókò Ìwé Ìbèrè, MHHS yóò gbà yóò sì ṣiṣẹ́ lórí ìbèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. Àkókò Ìwé Ìbèrè bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ tí a pèsè ìtọ́jú fún ẹnìkan ó sì parí ní ọjọ́ 240 lẹ́yìn déètì ìwé ìdíyelé àkọ́kọ́ fún ìtọ́jú náà.

3. *Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè (AGB)*: Àwọn aláìsàn tó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a kò ní díyelé fún ìtọ́jú pàtàkì ti ìlera àti pàjáwìrì ju iye tí a máa ń bèrè (AGB) lọ lọ́wọ́ àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò.

    a. Ìdá ọgọ́rùún AGB ti MHHS ni a ń ṣírò nípa lílo ìlànà "wo-ẹ̀yìn", èyí tó jẹ́ àpapọ̀ ti ìsanwó owó-fún-iṣẹ́ Medicare tí a gbà láàyè tí a sì pín nípa àpapọ̀ iye owó fún àwọn tí a bèrè ṣáájú ìgbà oṣù 12. Àwọn ẹ̀dínwó tí a pèsè fún àwọn aláìsàn tó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ó ṣàtúnyẹ̀wò sí òdíwọ̀n ìdá ọgọ́rùún AGB láti ṣàrídájú pé a kò díyelé àwọn aláìsàn ju AGB lọ.

    b. Ìdá ọgọ́rùún AGB ni a le rí ní Àfihàn A -Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè Ìṣirò ti FAP.

    c. Àtúnyẹ̀wo Ìdá Ọgọ́rùún AGB ni a ó ṣírò ní ọdọdún ni a ó sì ṣàmúlò ní ọjọ́ 120 lẹ́yìn Ìbẹ̀rẹ̀ kàlẹ́ndà ọdún.

4. *Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Ní Ọdún:* Àròpọ̀ owó Ẹbí kan láàrín ọdún àti ànfàní owó lọ́wọ́ láti orísun gbogbo ṣáájú owó-orí, yàtọ̀ sí owó díẹ̀ tí a san fún àtìlẹ́yìn ọmọ, tí a le jábọ̀ fún Iṣẹ́ Àgbàwọlé Abẹ́lé United States. Owó-àpawọlé ẹbí pẹ̀lú, ṣùgbọ́n kò pín sí, àwọn owó tí a gbà, owó àjẹmọ́nú àìníṣẹ́, owó àjẹmọ́nú òṣìṣẹ́, Àábò Ìgbàlódé, Owó-àpawọlé Àábò Aláfikún, ìrànlọ́wọ́ gbogbogbò, àwọn ìsanwó arúgbó, àwọn ànfàní ẹni tó yọ nínú ewu, owó-àpawọlé ìfẹ̀yìntì, owó èlé, owó ìpín, owó lẹ́yìn ìtúká ìgbeyàwó, àtìlẹ́yìn ọmọ, àti àwọn orísun míràn.

5. *Àwọn Iṣẹ́ Àṣàyàn:* Àwọn iṣẹ́ láti yanjú ìṣòro kan tí kò nílò abójútó ojú-ẹsẹ̀. Àwọn iṣẹ́

àṣàyàn kún àwọn ìlanà tó dára fún aláìsàn, ṣùgbọ́n kò jẹ́ kánjúkánjú ó sì pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ tó ṣe pàtàkì fún ìlera àti àwọn isẹ́ tó ṣe pàtàkì tí kìíṣe ti ìlera, bii oge àti iṣẹ́ abẹ eyin tí a ṣe nìkan láti ṣàmúgbòrò ojú tàbí àwọn ìlànà míràn tí a yàn èyítí kò sí lábẹ́ àwọn ètò ìdójútòfo ìlera. Àwọn iṣẹ́ àṣàyàn tí kò ṣe pàtakì fún ìlera ni a kò ní wòye fún Ìrànlọ́wọ́ Owó.

6. *Àwọn Iṣẹ́ pàjáwìrì:* Àwọn iṣẹ́ tí a pèsè fún aláìsàn kan fún àìsan kan pẹ̀lú àmì tó lágbára púpọ̀ (pẹ̀lú ìrora tó pọ̀ jù), èyítí ó jẹ́ wípé àìsí àbójútó ìlera lójú ẹsẹ̀ ni a rò wípé ó le yọrísí wípé fífi ìlera irú ẹni náà (tàbí èyi tó níṣe pẹ̀lú olóyún, obìnrin náà tàbí ọmọ tí a kò tíi bí) sí ewu ńlá, tàbí ṣokùnfà àlébù tó lágbára sí iṣẹ́ ara, tàbí àìle ṣiṣẹ́ mọ́ fún èyíkéyìí ẹ̀yà ara.

7. *Àwọn Ìṣe Gbígbà Ní Ọ̀nà Ọ̀tọ̀ (ECAs):* Èyí ni àwọn ìṣe gbígbà tó nílò ìlànà iṣẹ́ òfin àti ti adájọ́, ó sì tún le kan àwọn iṣẹ́ míràn bíi títa gbèsè fún ẹlomíràn tàbí jíjábọ̀ àlàyé tó léwu sí àwọn aṣojú kírẹ́dìtì tàbí ilé-iṣẹ́. MHHS kò ṣàmúlò ECAs, bẹ́ẹ̀ni kò gba àwọn aṣojú gbígbà rẹ̀ láti ṣàmúlò ECAs. Síwájú síi lórí àwọn òfin gbígbà MHHS ni a le rí nínú MHHS ti àwọn ẹ̀dà ọ̀fẹ́ Òfin Ìdíyelé àti Gbígbà; MHHS ọ̀tọ̀ ti òfin yìí wà lórí ayélujára ní: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/tàbí àwọn ẹ̀dà pépà ọ̀fẹ́ wà nílẹ̀ tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti agbègbè ìforúkọsílẹ̀ ilé-ìwosàn tàbí nípa pípe (713) 338-5502 tabí 1-800-526-2121, Àṣàyàn 5.

8. *Ẹbí:* Aláìsàn náà, olólùfẹ́ aláìsàn/alábàágbé ti ìjọba, àwọn òbí tàbí alágbàtọ́ aláìsàn (tó bá jẹ́ ọmọdé), àti èyíkéyìí ẹnití a ń bọ́ tí a bèrè lórí ìdápadà owó-orí àpawọlé ti òbí tàbí aláìsàn, tí ó sì ń gbé láàrín mọ̀lẹ́bí alágbàtọ́ tàbí òbí tàbí aláìsàn.

9. *Ipele Àìní Ìjọba (“FPL”)*: Ipele owó-àpawọlé tó yẹ ki ẹnìkan wà nínú ipele ìwọ̀n àìní. Owó-àpawọlé yìí yàtọ̀ nípasẹ̀ ìwọ̀n ìpín ẹbí náà. A ń ṣàfikún ipele àìní náà ní ọdọdún nípasẹ̀ Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ọmọnìyàn àti Ìlera ti United States tí a sì tẹ̀jáde nínú Àkọsílẹ̀ Ìjọba Àpapọ̀. Fún àwọn èrèdí FAP yìí , ipele àìní tí a ṣàfihàn nínú àwọn ìtọ́ni tí a tẹ̀jáde wọ̀nyí ṣojú àpapọ̀ owó-àpawọlé. FPL tí a lò fún àwọn èrèdí FAP yìí ni a ó máa ṣàfikún ní ọdọdún.

    a. Àwọn FPL ìsinsìnyí ni a le rí ní Àfihàn B - Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọbà ti FAP.

10. *Ìrànlọ́wọ́ Owó:* Ìrànlọ́wọ́ Owó túmọ̀ sí ìrànlọ́wọ́ tí MHHS ń fún àwọn aláìsàn tó yẹ fún àwọn amúyẹ owó kan pàtó àti àwọn ohun àmúyẹ míràn bí a ti túmọ̀ nínú FAP láti ràn wọ́n lọ́wọ́ láti gba àwọn ohun àmúlò owó tó ṣe pàtàkì láti san fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtakì tàbí pàjáwìrì èyítí MHHS ń pèsè nínú ètò ilé-ìwòsàn kan. Àwọn aláìsàn tó yẹ le kan àwọn aláìsàn tí kò ní ètò ìdójútòfò, àwọn aláìsàn tí owó-àpawọlé wọn kéré, àti àwọn aláìsàn tó ní ààbò díẹ̀ ṣùgbọ́n tí wọn kò le sanwó díẹ̀ tàbí gbogbo àwọn ìdíyelé ìlera wọn tó kù.

11. *Àwọn Iṣẹ́ Ìlera Tó Ṣe Pàtàkì*: Àwọn iṣẹ́ tabí ohun èlò tí a pèsè fún àyẹ̀wò, ìtọ́jú tààrà, àti ìtọ́jú àìsàn kan, ṣe déédé fún gbèdéke iṣẹ́ ìlera tó péye ní àdúgbò abẹ́lé, ni ó wà lábẹ́ tí a sì ríi bí èyítí ó ṣe patàkì fún ìlera nípasẹ̀ Medicare àti àwọn ètò Medicaid, kò sì wà fún ìrọ̀rùn aláìsàn tàbí dókítà nikan. Àwọn iṣẹ́ tó ṣe pàtàkì fún ìlera kò kan iṣẹ́ abẹ fún oge tabí àwọn iṣẹ́ tí kìíṣe ti ìlera, bíi àwọn iṣẹ́ ìkẹ́gbẹ́, ẹ̀kọ́

tàbí iṣẹ́-ọwọ́.

12. *Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán (“PLS”)*: Ìsọníṣókí èdè tódán mọ́rán ti FAP MHHS pẹ̀lú: (a) àlàyé díẹ̀ ti àwọn ohun àmúyẹ àti ìrànlọ́wọ́ tí a ń fúnni; (b) àkójọ ti ojúlé wẹ́ẹ̀bù àti ibi tí wọ́n wà tí a ti le gba àwọn ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó; (c) àwọn ìtọ́ni lórí bí a ti le gba ẹ̀dà pépà ọ̀fẹ́ ti FAP; (5) àlàyé olùbásọ̀rọ̀ fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú ìlànà ìbéèrè; (6) wíwà nílẹ̀ fún ìtúmọ̀ èdè ti FAP àti àwọn ìwé míràn tójọra; àti (7) gbólóhùn ijẹ́rìísi pé àwọn aláìsàn tí a pinnu pé wọ́n yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a kò ní díyelé ju iye owó tí a ń bèrè fún pàjáwìrì tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtàkì.

13. *Àmúyẹ Tí A Rò tàbí Èyítí A Rò Pé Ó yẹ:* Ìpinnu àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó tí a ṣe nípa ìtọ́kasí àmúyẹ kan pàtó èyítí a ti rò láti ṣàfihàn àìní owó lọ́dọ̀ aláìsàn kan tí kò ní ìdójútòfò láì parí ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó kan.

14. *Àwọn Ìgbésẹ̀ Tó Ní Ìtumọ̀:* MHHS yóo gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó ní ìtumọ̀ láti pèsè àlàyé fún aláìsàn nípa FAP ti MHHS nípa fífún àwọn aláìsàn ní Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán ti FAP sí aláìsàn ṣáájú kí a tó fi sílẹ̀ ní ilé-ìwosàn. Ní àfikún, MHHS yóò gbé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí láti wífún àwọn aláìsàn nípa MHHS FAP.

    a. *Àwọn Ìwé Ìbèrè Tí Kò Péye:* Tí aláìsàn náà àti/tàbí Ẹbí bá fa ìwé ìbèrè tí kò péye kalẹ̀, MHHS yóò pèsè ìfitónilétí tí a fọwọ́kọ tí ń ṣàlàyé irú àfikún àlàyé tàbí ìwé àkọsílẹ̀ tó nílò.

    b. *Àwọn Ìwé Ìbèrè Tó Péye:* Tí aláìsàn náà àti/tàbí Mọ̀lẹ́bí aláìsàn náà bá fa ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó kalẹ̀, MHHS yóò pèsè

       ìfitónilétí àfọwọ́kọ tí ń sọ nípa ìpinnu yálà aláìsàn náà yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ní àkókò tó yẹ yóò sì sọ fún aláìsàn náà ní kíkọ nípa ìpinnu (pẹ̀lú, tó bá yẹ, ìranlọ́wọ́ fún èyítí aláìsàn náà yẹ fún) àti àwọn ìdí fún ìpinnu yìí. Ìfitónilétí yìí yóò tún pẹ̀lú iye ìdá ọgọ́rùún Ìrànlọ́wọ́ Owó (fun àwọn ìwé ìbèrè tí a fọwọ́sí) tàbí (àwọn) ìdí fún sísẹ́, àti iye owó sísan tí a ń retí lọ́wọ́ aláìsàn náà àti/tàbí Ẹbí tó bá wà. Aláìsàn náà àti/tàbí Ẹbí yóò máa gba àkọsílẹ̀ owó ní àkókò àyẹ̀wò ti ìwé ìbèrè tó parí.

    c. *Àwọn Àkọsílẹ̀ Owó Aláìsàn:* MHHS yóo fi oríṣìí àkọsílẹ̀ owó ránṣẹ́ tí ń ṣàlàyé àkọ́ọ́lẹ̀ aláìsàn àti iye tó yẹ láti san. Àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn yóo pẹ̀lú ìbèrè kan wípé ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti wífún MHHS nípa wíwànílẹ̀ èyíkéyìí ààbò iṣẹ́ ìdójútòfò ìlera kan, àkíyèsí MHHS FAP, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ kan láti bèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti àdírẹ́sì ojúlé-wẹ́ẹ̀bù níbití a ti le gba àwọn ìwé àkọsílẹ̀ FAP.

    d. *Ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHHS:* Àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSS yóò ṣe àgbéjáde àkíyèsí ní àwọn ibití ó ṣe pàtàkì tí Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀, pẹ̀lú àlàyé ìlànà iṣẹ́ ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. MHHS yóò ṣàgbéjáde FAP yìí pẹ̀lú àkójọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti àwọn tí kò sí lábẹ́ FAP, ìsọníṣókí èdè tódán mọ́rán, ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Òfin Ìdíyelé àti Gbígbà  lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti

MHHS: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/. MHHS yóò ní àwọn ẹ̀dà pépà ọ̀fẹ́ ti àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wọ̀nyí nílẹ̀ tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀.

15. *Aláìsàn tí Ìdójútòfò rẹ̀ kò péye:* Aláìsàn kan tó ní ààbò díẹ̀ tàbí pátápátá lábẹ́ òfin kan ti ìdójútòfò tó jẹ́ nípa gbígba ìtọ́jí pàtàkì ti ìlera tàbí pàjáwìrì ní àwọn ináwó tó kọjá agbára wọn láti san owó tókù fún ìtọ́jú tí wọn ń gbà.

16. *Aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò:* Aláìsàn kan tí kò ní ààbò díẹ̀ tàbí rárá lábẹ́ òfin ti ìdójútòfò ìlera tí kìíṣe ẹnití ń jẹ ànfàní lábẹ́ ìdójútòfò ìlera àdáni tàbí ti ìjọba, ànfàní ìlera, tàbí ètò ààbò ìlera míràn (pẹ̀lú, láìsí òdiwọ̀n, ìdójútòfò àdáni, Medicare, tàbí Medicaid, tàbí Ìrànlọ́wọ́ Ẹnití A Dá Lọ́ràn) àti tí ọgbẹ́ rẹ̀ ko ní owó àjẹmọ́nú nínú fún àwọn èrèdí owó àjẹmọ́nú òṣìṣẹ́, ìdójútòfò ọkọ̀, tàbí gbèsè tàbí ìdójútòfò ẹlomíran, bí MHHS ti pinnu èyítí ó dá lórí àwọn àkọsílẹ̀ àti àlàyé tí a pèsè nípa aláìsàn náà tàbí tí a gbà lati àwọn orísun míràn, fún ìsanwó awọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera èyítí MHHS ń pèsè.

**<u>ÀMÚYẸ ÀTÚNYẸ̀WÒ:</u>**

1. *Ìbánisọ̀rọ̀:* Láti jẹ́ kí àwọn aláìsàn, ẹbí, àti àpapọ̀ àdúgbò mọ̀ nípa wíwànílẹ̀ Ìrànlọ́wọ́ Owó, MHHS yóò gbé oríṣìí ìgbésẹ̀ láti wífún àwọn aláìsàn àti alèjò sí ilé-ìwòsàn rẹ̀ nípa ti wíwànílẹ̀ Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti láti ponlogo FAP yìí sí awọn ará àdúgbò èyítí ilé-ìwòsàn kọ̀ọ̀kan ń sìnrún fún. Àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí pẹ̀lú:

    a. *Ìyọ́nda Aláìsàn:* Ìyọ̀nda ìtọ́jú ìlera èyítí a buwọ́lù nígbàtí a ń forúkọsílẹ̀ fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera pẹ̀lú kan gbólóhùn kan wípé tí a bá nílò iṣẹ́ àánú, ìpinnu àmúyẹ ni a gbọ́dọ̀ bèrè fún tí a bá fẹ́ gba ẹni náà wọ ilé-ìwosàn náà tàbí tí a bá ti gba ìwé ìdíyelé ohun tí a kọ tàbí àkọsílẹ̀ owó.

    b. *Ìdámọ̀ràn Owó:* A gba àwọn aláìsàn MHHS nímọ̀ràn láti wá àlàyé láti ọ̀dọ̀ olùdámọ̀ràn owó ti ilé ìwòsan wọn tí wọ́n bá ń dojúkọ ìṣòro láti sanwó fún gbèsè wọn ní ilé-ìwòsàn. Àwọn olùdámọ̀ràn owó wa yóò tiraka láti ran àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò, tí ìdójútòfò rẹ̀ kò péyé, tàbí tí n dojúkọ àwọn ìpèníjà owó tó níṣe pẹ̀lú sísan owó àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tí a pèsè lọ́wọ́. Àwọn olùdámọ̀ràn owó le tọpinpin àwọn aláìsan fún àmúyẹ fún oríṣìí àwọn ètò owó tí ìjọba gbésílẹ̀, ṣe ìrànwọ́ fún owó àjẹmọ́nú ti òṣìṣẹ́ tàbí ìbèrè gbèsè, ṣètò ìgbà ìsanwó tí a fàgùn, tàbí ṣèrànwọ́ fún àwọn aláìsàn láti bèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó.

    c. *Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán àti Ìwé Ìbèrè:* Ẹ̀dà pépà kan ti isọníṣókí èdè tódán mọ́rán ti FAP ti MHHS àti ẹ̀dà pépà kan ti ìwé ìbèrè Ìranlọ́wọ́ Owó ni yóò wà nílẹ̀ fún gbogbo àwọn aláìsàn tí ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ àkókò iṣẹ́ àṣehàn wọn. MHHS yóò ní àwọn ẹ̀dà pépà ọ̀fẹ́ ti àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wọ̀nyí nílẹ̀ tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀. Àwọn ẹ̀dà pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ nípasẹ̀ lẹ́tà tabi nípa pípe (713) -338-5502 tàbí 1-800-526-2121, Àṣàyàn 5.

d. *Àwọn Ẹ̀dà Tí A Túmọ̀ Wàníl̀ẹ:* MHHS ń túmọ̀ FAP rẹ̀, Ìsọnişókí Èdè Tódán Mọ́rán, ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Ìdíyelé àti Gbígbà Òfin fún àwọn tó le sọ èdè Gẹ̀ẹ́sì dáradára èyí tí kò tó ìdá márùún nínú ọgọ́rùún (5%) tàbí 1,000 àwọn ènìyàn ti agbègbè èyítí ohun èlò ilé-ìwòsàn náà ń sìnrú fún. MHHS jẹ́ kí àwọn ẹ̀dà àkọsílẹ̀ wọ̀nyí wà nílẹ̀ lọ́fẹ̀ẹ́ lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHHS àti tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀ ti ilé-ìwosàn. Àwọn ẹ̀dà pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ nípasẹ̀ lẹ́tà tabi nípa pípe (713) -338-5502 tàbí 1-800-526-2121, Àṣàyàn 5.

e. *Àmì:* Gbogbo àmì Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ó ṣàfihàn dáradára ní àwọn ibi tó ṣeé rí sí gbogbo ènìyàn, àti pẹ̀lú, ṣùgbọ́n kìíṣe sí ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì MHHS àti àwọn ibi ìforúkọ́sílẹ̀ aláìsàn nìkan. Àmì náà yóò tọ́ka pé Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀ àti nọ́mbà fóònù láti fi bá olùdámọ̀ràn owó sọ̀rọ̀ fún àlàyé síwájú síi.

f. *Ojúlé wẹ́ẹ̀bù:* Àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSS yóò ṣe àgbéjáde àkíyèsí ní àwọn ibití ó ṣe pàtàkì tí Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀, pẹ̀lú àlàyé ìlànà iṣẹ́ ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. MHHS yóò ṣàgbéjáde FAP rẹ̀ pẹ̀lú àkójọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti àwọn tí kò sí lábẹ́ FAP, Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán, ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Ìdíyelé àti àti Gbígbà lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti MHHS: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/.

g. *Àwọn ìdíyelé aláìsàn àti àkọsílẹ̀ owó:* Àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn yóo pẹ̀lú ìbèrè kan wípé ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti wífún MHHS nípa wíwàníl̀ẹ èyíkéyìí ààbò iṣẹ́ ìdójútòfò ìlera kan, yóò sì kan àkíyèsí MHHS FAP, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ kan láti bèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti àdírẹ́sì ojúlé-wẹ́ẹ̀bù níbití a ti le gba àwọn ìwé àkọsílẹ̀ Ìrànlọ́wọ́ Owó.

h. *lẹ́tà tàbí fakisi:* Àwọn aláìsàn ìbèrè àfọwọ́kọ wọn ṣọwọ́ nípasẹ̀ lẹ́tà tàbí fakisi lọ́fẹ̀ẹ́ fún àwọn ẹ̀dà àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wọ̀nyí lọ́fẹ̀ẹ́ sí àdírẹ́sì tó wà nísàlẹ̀ tó sì ni ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ orúkọ ẹni náà àti àdírẹ́sì ìdápadà sí èyítí wọ́n fẹ́ kí MHHS fi àwọn ẹ̀dà náà ránṣẹ́ sí.

Memorial Hermann Health System
Attn: Financial Assistance
909 Frostwood
Suite 3:100
Houston, Texas 77024
FAKISI: 713-338-6500

2. *Ìpinnu Àmúyẹ:* Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ń pinnu gẹ́gẹ́ bí ilànà tó kan àyẹ̀wò oníkálùkù nípa bí wọ́n ti nílò owó sí. Àwọn ìlànà náà ni a ṣàlàyé nísàlẹ̀:

   a. Ìpinnu Àmúyẹ Tí a Rò ni a parí gẹ́gẹ́ bíi ohun àmúyẹ tí a ṣàlàyé nínú Ìlànà Abala 4 nísàlẹ̀. Tí a bá Rò wípé aláìsàn kan yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó, èyí kò nílò ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. Ṣùgbọ́n, aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà náà gbọ́dọ̀ sowọ́pọ̀ mọ́ ìlanà ìtọpinpin náà kó si fún wa ní àlayé nípa owó tàbí ara rẹ̀ àti

àwọn ìwé ẹ̀rí tó ṣe pàtàkì láti ṣe ìpinnu ti Àmúyẹ Tí A Rò.

b. Ìlànà ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, nínu èyítí aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà gbọ́dọ̀ sowọ́pọ̀ kó si fún wa ní àlayé nípa owó tàbí ara rẹ̀ àti àwọn ìwé ẹ̀rí tó ṣe pàtàkì láti ṣe ìpinnu ti àìní owó;

c. MHHS yóò tiraka láti pinnu bóyá ẹnìkan yẹ fún FAP láti kan pípèsè ìfitónilétí fún aláìsàn náà nípa FAP ti MHHS nínú Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán ṣáájú kí a tó fi wọ́n sílẹ̀ ní ilé-ìwòsàn. Ní àfikún, MHHS yóò gbé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí láti wífún àwọn aláìsàn nípa FPA ti MHHS.

   i. *Àwọn Ìwé Ìbèrè Tí Kò Péye:* Tí aláìsàn náà àti/tàbí Ẹbí bá fa ìwé ìbèrè tí kò péye kalẹ̀, MHHS yóò pèsè ìfitónilétí tí a fọwọ́kọ tí ń ṣàlàyé irú àfikún àlàyé tàbí ìwé àkọsílẹ̀ tó nílò láàrín ọjọ́ márùn lé lógójì (45) tí a gba ìwé ìbèrè àkọ́kọ́.
   ii. *Àwọn Àkọsílẹ̀ Owó Aláìsàn:* Àwọn gbolóhùn aláìsàn yóò pẹ̀lú gbólóhùn wípé aláìsàn náà gbọ́dọ̀ sọ fún MHHS nípa èyíkéyìí ààbò ìdójútòfò ìlera yóò sì pẹ̀lú àkíyèsí kan ti MHHS FAP, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ láti bèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti àdírẹ́sì ojúlé wẹ́ẹ̀bù níbití a ti le gba àwọn ìwé FAP.
   iii. *Ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHHS:* Àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSS yóò ṣe àgbéjáde àkíyèsí ní àwọn ibití ó ṣe pàtàkì tí Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀, pẹ̀lú àlàyé ìlànà iṣẹ́ ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. Lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHHS náà: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/, MHHS yóò ṣàgbéjáde FAP rẹ̀ pẹ̀lú àkójọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti àwọn tí kò sí lábẹ́ FAP, Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán, ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Ìdíyelé àti Òfin Gbígbà rẹ̀.
   iv. *Àwọn Ìwé Tó Wà Nílẹ̀ tí a bá Bèrè:* MHHS yóò ní, àwọn ẹ̀dà ti FAP rẹ̀ pẹ̀lú àkójọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti tí kò sí lábẹ́ FAP, Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán, ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Ìdíyelé àti Gbígbà Òfin rẹ̀ nílẹ̀ lọ́f ẹ̀ẹ́ nígbàtí a bá bèrè fún un ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀.

d. Ìlò àwọn orísun dátà tó wà nílẹ̀ fún gbogbo ènìyàn lóde èyítí ń pèsè àlàyé lórí agbára aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà kan lati sanwó pẹ̀lú iye kírẹ́dìtì nípasẹ̀ TransUnion tàbí Experian;

e. Àtúnyẹ̀wò àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ gbèsè aláìsàn tí a gbà fún àwọn iṣẹ́ ti a ṣe ní MHHS àti ìsanwó aláìsàn tàbí ìtàn gbèsè tí kò le san;

f. Àwọn ipele Ìrànlọ́wọ́ Owó tí MHHS ti pèsè tó dá lórí owó àpawọlé, bí Ẹbí ti pọ̀ tó, àti FPL. Àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò àti àwọn tí kò ní le bèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó; àti

g. Àmúyẹ aláìsàn fún Ìrànlọ́wọ́ Owó yóò dá lórí ohun àmúyẹ nísàlẹ̀ ó sì le yàtọ̀ èyí dá lórí ipò owó aláìsàn, àwọn àyídà owó tó ní ìdí àti wíwà nílẹ̀ ti ẹlòmíràn

àwọn ànfàní ìtọ́jú ìlera. Àwọn ìtọ́ni àmúyẹ ni a ó máa ṣàtúnyẹ̀wò ní ọdọdún lẹ́yìn tí ìjọba àpapọ̀ bá ti ṣàtẹ̀jáde àwọn ìtọ́ni FPL. Àwọn ẹbí tó ní owó-àpawọlé tó kọjá ìtọ́ni tí a kọ sísàlẹ̀ ni a ó tọpinpin fún àgbéyẹ̀wò ètò ìsanwó.

3. *Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó Aláìsàn:* Èyí tó dá lórí FPL, àwọn ohun àmúyẹ wọ̀nyí ni a ó lo láti ìnnu àwọn ẹ̀dínwó tí a fifún Àwọn Aláìsàn tí kò ní Ìdójútòfò àti Àwọn tó ní ṣùgbọ́n tí kò péye tó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. Àwọn Aláìsàn Tó Ní Ìdójútòfò tí kò péye gbọ́dọ̀ ní ìdíyéle ìdójútòfò wọn kí wọ́n tó yẹ fún iṣẹ́ àánú. Àwọn ẹ̀dínwó tí a pèsè fún àwọn aláìsàn tó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ó ṣàtúnyẹ̀wò sí òdíwọ̀n ìdá ọgọ́rùún AGB láti ṣàrídájú pé a kò díyelé àwọn aláìsàn ju AGB lọ.

   a. **Ìtọ́jú Ọ̀fẹ́:**

      i. Tí Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Láàrín Ọdún fún aláìsàn náà bá jẹ́ tàbí kéré sí ìdá ọgọ́rùún igba (200%) ti Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀, bí a ti ṣètò rẹ̀ nínú Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó Àpapọ̀ Owó-àpawọlé (Àfihàn A -Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè Ìṣirò), aláìsàn náà (tàbí àwọn míràn tó le yẹ) yóò lẹ́tọ̀ọ́ sí ìtọ́jú ọ̀fẹ́ (ẹ̀dínwó 100%) kò sì ní jẹ ìdá kankan nínú ìyókù àkọọ́lẹ̀ lówó.

      ii. Àwọn alaìsàn tó ní ààbò ìlera àkọ́kọ́ nípasẹ̀ Medicare tí wọ́n sì yẹ fún ààbò ìlera kejì nípasẹ̀ Medicaid yóò gba ẹ̀dínwó ọgọ́rùún nínú ìdá ọgọ́rùún (100%) lórí èyíkéyìí ìyókù owó tó bá kù lẹ́yìn tí a díyelé Medicaid tí a sì gba ìbèrè tí a yanjú láti THMP tàbí olùsanwó Medicaid Tí a ṣàkóso.

   b. **Ìtọ́jú Ẹ̀dínwó:**

      i. Àwọn Aláìsàn/ẹnìkan tí Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Láàrín Ọdún kọjá igba nínú ìdá ọgọ́rùún (200%) ṣùgbọ́n tí kò kọjá irinwó ìdá ọgọ́rùún (400%) tí Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀ ti ìsinsìnyí le yẹ fún ẹ̀dínwó ti àwọn ìdíyelé sí iye owó tí a máa ń bèrè (AGB) sí àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò.

      ii. Àwọn aláìsàn tó ní gbèsè nínú àkọọ́lẹ̀ wọn tí wọ́n jẹ sí ìdíyelé ilé-ìwòsàn wọn le yẹ fún ẹ̀dínwó tí wọ́n bá kójú ìwọ̀n fún àwọn ohun àmúyẹ wọ̀nyí: 1) ìyókù owó tó kọjá mẹ́wàá nínú ìdá ọgọ́rùún (10%) tí Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Láàrín Ọdún tí ẹni náà; 2) wọn kò le san gbogbo owó tàbí díẹ̀ nínú ìyókù ìdíyelé tó kù; àti 3) àti ìyókù ìdíyelé tó jẹ́ ó kéré jù $5,000. Lábẹ́ àwọn ìṣàkóso wọ̀nyí, aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà náà gbọ́dọ̀ sowọ́pọ̀ mọ́ ìlanà FAP náà kó si fún wa ní àlayé nípa owó tàbí ara rẹ̀ àti àwọn ìwé ẹ̀rí tó ṣe pàtàkì láti ṣe ìpinnu ti àmúyẹ. Tí a bá buwọ́lùú, aláìsàn náà kò ní san ju mẹ́wàá nínú ìdá ọgọ́rùún (10%) ti Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Láàrín Ọdún wọn lọ fún ìyókù gbèsè inú àkọọ́lẹ̀ tàbí kí a lò ẹ̀dínwo AGB, èyíkéyìí tó bá kéré tó sì dára jùlọ fún ipò owó aláìsàn náà.

4. *Àmúyẹ Tí A Rò:* A le pinnu àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò pé ó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́

Owó èyítí ó dá lórí wíwà nílẹ̀ ti ọ̀kan nínú àmúyẹ tí a kọ sísàlẹ̀. Lẹ́yìn tí ó bá ti ṣàfihàn ó kéré jù àmúyẹ kan, a kò ní bèrè ẹ̀rí owó-àpawọlé kankan mọ́. Àkójọ ìsàlẹ̀ yìí jẹ́ aṣoju àwọn àyídà nínu èyítí Owó-àpawọlé ẹbí alaìsàn kan kéré ju ìgbà méjì FPL lọ àti pé aláìsàn náà yẹ fún ẹ̀dínwó ọgọ́rùún nínú ìdá ọgọ́rùún (100%) tí àwọn ìdíyelé pàtàkì fún ìlera. Ìtọpinpin Àmúyẹ Tí A Rò fún aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò ni a gbọ́dọ̀ parí ní kíákíá lẹ́yìn tí a gba àwọn iṣẹ́ pàtàkì fún ìlera tó sì ṣáájú ìfúnni ní ìdíyelé fún àwọn iṣẹ́ náà. Nígbàtí a bá sọ fún wa nípa ipò Àmúyẹ Tí A Rò, MHHS yóò di Gbólóhùn Aláìsan mú fún ọgbọ̀n ọjọ́ (30) ní àkókò ìparí ìlàna àtúnyẹ̀wò Àmúyẹ Tí A Rò. Àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò míran (yàtọ̀ sí àwọn ètò ìrànwọ́ ìjọba abẹ́lé tàbí ìpínlẹ̀ bíi Medicaid) ni a kò ní ṣàgbéyẹ̀wò fún Àmúyẹ Tí A Rò a ó sì bèrè láti fa ìwé ìbèrè fún ìrànlọ́wọ́ owó kalẹ̀.

a. Àwọn aláìsàn tí kò ni ìdójútòfò tó sì bá àwọn àmúyẹ wọ̀nyí mu ni a ó rí bíi Àmúyẹ Tí A Rò fún ẹ̀dínwó ọgọ́rùún nínú ìdá ọgọ́rùún (100%) tí àwọn ìdíyele'pàtakì fún ìlera tàbí pàjáwìrì:

    i. Àìnílé tàbí ìtọ́jú tí a gbà láti ilé-ìwòsàn aláìnílé;
    ii. Ìkópa nínú àwọn ètò Àwọn Obìnrin, Ọmọ ọwọ́ àti Ọmọdé (WIC);
    iii. Àmúyẹ èdìdí oúnjẹ;
    iv. Ètò Ìrànlọ́wọ́ Oúnjẹ Aṣaralóore Aláfikún;
    v. Àmúyẹ fún àwọn ètò ìrànwọ́ ìjọba abélé tàbí ìpínlẹ̀ míràn (fún àpẹrẹ, Medicaid náwó-díẹ̀);
    vi. Owó-àpawọlé díẹ̀/ẹ̀dínwó ilé-gbígbé ni a ń pèsè bíi àdírẹ́sì tó péye;
    vii. Ìwé ẹ̀rí fún ìrànlọ́wọ́ tí a fúnni fún àwọn iṣẹ́ ìlera;
    viii. Àìlágbára ní iṣẹ́ ọpọlọ láìsí ẹnikẹ́ni láti dúró lórúkọ rẹ;
    ix. Gbèsè-jíjẹ àdáni àìpé
    x. Àfipamọ́ fún ìwà ọ̀daràn;
    xi. Aláìsàn tó kú láì mọ ipò kan; tàbí
    xii. Bí ẹ̀yà ìgbéléwọ̀n orí-ẹ̀rọ náà bá ti pinnu (tí a ṣàlayé nísàlẹ̀).

b. **Ẹ̀yà Ìgbéléwọ̀n Orí-ẹ̀rọ:** Nígbàtí Aláìsàn tí kò ní Ìdójútòfò kan bá kùnà láti parí ìwé ìbèrè FAP tàbí tí kò pèsè àwọn ìwé àkọsílẹ̀ ìṣúná owó tí a bèrè fún èyí tó ṣe pàtàkì láti pinnu àmúyẹ, a le tọpinpin àkọ́ọ́lẹ̀ náà nípa lílo ẹ̀yà ìgbéléwọ̀n orí-ẹ̀rọ (ESM) èyítí ń ṣe ìṣirò tó dá lórí àmúyẹ láti pẹ̀lú ipele ìṣúná, àtúnṣe iṣẹ́ àánú ti tẹ́lẹ̀, iṣẹ́-ṣíṣe, kóòdù ìfiwéránṣẹ́, ọjọ́-orí, ìtàn ìsanwó, gbèsè àìlesan ti tẹ́lẹ̀, ìyókù owó àkọ́ọ́lẹ̀, àti orísun ìgbàwọlé. Tí iye ESM náà bá ṣàfihàn ìdánilójú tó dára àkọ́ọ́lẹ̀ náà yóò yẹ fún FAP, àkọ́ọ́lẹ̀ náà tí kò ni ìdójútòfò ni a ó fún ní ẹ̀dínwó FAP tí a rò gẹ́gẹ́ bíi FAP yìí.

5. *Gbèdéke Àmúyẹ:*

    a. Fún àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò, àwọn ìpinnu Àmúyẹ Tí A Rò àti Ìrànlọ́wọ́ Owo yóò muná dóko lẹ́yìn ọ̀pọ̀ èrò fún gbogbo àwọn ìyókù owó àdásan àti ìṣẹ̀lẹ̀ ìtọ́jú ìsinsìnyí. A ó pinnu àmúyẹ àwọn aláìsàn èyí tó dá lórí àwọn ohun tí a là kalẹ̀ nínú Ìlànà Abala 3 kò sì ní léwu fún sísanwó kíá àti ní àkókò. Ní àfikún, fún aláìsàn tó parí Ìwé Ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ó fún ní àfikún

ìrànlọ́wọ́ owó fún oṣù mẹ́fà láìsí ìgbésẹ̀ kankan mọ́ tí aláìsàn náà nílò. Aláìsàn náà yóò bá MHHS sọ nípa èyíkéyìí àyípadà ohun ìní nínú ipò owó aláìsàn náà tó wáyé ní àkókò oṣù mẹ́fà (6) náà èyí tó le kan ìpinnu àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó láàrín ọgbọ̀n ọjọ́ (30) ti àyípadà náà. Ìkùnnà aláìsàn kan láti ṣàfihàn ìmúdàgbà ohun ìní nínú owó-àpawọlé le pàdánù èyíkéyìí ìpèsè ti Ìrànlọ́wọ́ Owo nípasẹ̀ MHHS lẹ́yìn tí ìmúdàgbà ohun ìní ti wáyé.

6. *Àwọn Iṣẹ́ Pàtàkì ti Ìlera tàbí Pàjáwìrì:* Ìrànlọ́wọ́ owó ní òdíwọ̀n sí àwọn iṣẹ́ pàtàkì ti ìlera àti pàjáwìrì tí a ṣe nínú ilé-ìwòsàn kan. Kò sí ohunkóhun nínú abala yìí tí yóò ṣàyípadà àwọn òjúṣe àti ìlépa àwọn ìṣe MHHS sí òfin ìjọba ìpínlẹ̀ tàbí ti àpapọ̀ nípa ìtọ́jú ipò àìsàn pàjáwìrì láìsí agbára fún aláìsàn láti sanwó.

7. *Ìlànà Ìwé Ìbèrè*

   a. *Bí a ti le Bèrè:* O gbọ́dọ̀ parí ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó kí o sì fàá kalẹ̀, pẹ̀lú àwọn ìwé ẹ̀rí tí a bèrè fún. Àwọn ẹ̀dà ọ̀fẹ́ ti ìwé ìbèrè wà nílẹ̀ fún gbígbàsílẹ̀ lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ní MHHS: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/. Àwọn ẹ̀dà pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn agbègbè ìforúkọsílẹ̀ ilé-ìwòsàn. Àwọn ẹ̀dà pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ nípasẹ̀ lẹ́tà tabi nípa pípe (713) -338-5502 tàbí 1-800-526-2121, Àṣàyàn 5.

   b. Àwọn olùbèrè le fi ìwé ìbèrè tó parí àti àwọn ìwe àkọsílẹ̀ tí a bèrè fún ránṣẹ́ sí olùdámọ̀ràn owó ti ilé-ìwòsàn tàbí fi lẹ́tà wọn sí àdírẹ́sì tó wà ní ìsalẹ̀. Àwọn aláìsan le wá olùdámọ̀ràn owó ilé-ìwòsàn kan nípa ṣíṣe àbẹ̀wò sí ibi àlàyé kí o sì bèrè láti bá olùdámọ̀ràn owó sọ̀rọ̀. Fún àwọn ìbéèrè nípa ìlànà ìwé ìbèrè, ìrànlọ́wọ́ láti fọwọ́sí ìwé ìbèrè, tàbí ṣàyẹ̀wò ipò ìwé ìbèrè tí a fàkalẹ̀, àwọn olùdámọ̀ràn owó ti ilé-ìwosàn wà nílẹ̀ láti ṣèranwọ́ lójúkojú ní ilé-ìwòsàn tàbí o le pe 713-338-5502 tàbí 1-800-526-2121, Àṣàyàn 5.

   c. Ibi tí a le fi àwọn ìwé ìbèrè tó péye ṣọwọ́ sí:

Memorial Hermann Health System
Attn: Financial Assistance
909 Frostwood
Suite 3:100
Houston, Texas 77024

-TÀBÍ-

FAKISI: 713.-338-6500

   d. Àwọn ìbèrè fún àgbéyẹ̀wò fún Ìrànlọ́wọ́ Owó tàbí Àmúyẹ Tí A Rò ni a le bẹ̀rẹ̀ nípasẹ̀ èyíkéyìí àwọn ènìyàn wọ̀nyí láàrín Ìgbà Ìwé Ìbèrè: (i) aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà; (ii) aṣojú aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà; (iii) àṣojú MHHS lórúkọ aláìsàn/iwé ìbèrè; tàbí (iv) dókítà tí ń tọ́jú aláìsàn náà.

e. Síbẹ̀síbẹ̀ àwọn àgbéyẹ̀wò tí a kọsílẹ̀ níbò míràn nínú FAP, ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àti láti kópa nínú ìlànà ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. Èyí pẹ̀lú pípèsè àlàyé nípa ààbò ìlera ẹlòmíràn tó wà nílẹ̀; tí a ń pèsè ní àkókò àti ní ọ̀nà tó dára gbogbo ìwé àkọsílẹ̀ àti ìw;e ẹ̀rí ti a nílò láti bèrè fún owó nípasẹ̀ ìjọba tàbí àwọn èto míràn (fún àpẹrẹ, Medicare, Medicaid, gbèsè ẹlòmíràn, Owó Ẹnití a dá lọ́ràn, abbl.) tàbí láti pinnu àmúyẹ aláìsàn náà fún Ìrànlọ́wọ́ Owó míràn. Ìkùnnà láti ṣe bẹ́ẹ̀ le nípa lórí àgbéyẹ̀wò ìwé ìbère Ìrànlọ́wọ́ Owó ti aláìsàn. A bèrè lọ́wọ́ aláìsàn láti pèsè àlàyé, ìwé ẹ̀rí ati àwọn àkọsílẹ̀ láàrín ọgbọ̀n ọjọ́ (30) ti ìbèrè MHHS àyàfi tí a bá fi àwọn àyídà kan tó ṣe dandan tó MHHS létí. Àyàfi ní ìṣẹ̀lẹ̀ Àmúyẹ Tí A Rò, ìwé ìbèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a gbọ́dọ̀ parí kí aláìsan náà sì buwọ́lùú (tàbí olùfọwọ́sọ̀yà/aṣojú).

f. Olùdámọ̀ràn owó kan le ṣèrànwọ́ fún olùbèrè ní àkókò ìbèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. Tí aláìsàn náà bá ti kú tí a kò sì dá ẹni tó yẹ mọ̀, aṣojú MHHS kan le ṣàgbéjáde ìbèrè kan kí o sì fọwọ́sí ìwé ìbèrè nípa lílo àlàye àti àwọn ìwé àkósílẹ̀ tó wà nílẹ̀.

8. *Owó-àpawọlé Ẹbí:*

a. Aláìsàn náà le pèsè ọ̀kan tàbí ọ̀pọ̀ nínú àwọn ìwé akọsílẹ̀ wọ̀nyí láti fìdí owó-àpawọlé múlẹ̀, tí irú àwọn ìwé àkọsílẹ̀ bá wà nílẹ̀. Tí a bá ní ju ẹnìkan tí ń ṣiṣẹ́ lọ nínú Ẹbí aláìsàn, ẹnikọ̀ọ̀kan gbọ́dọ̀ fa ọ̀kan tàbí ọ̀pọ̀ àwọn ìwé àkọsílẹ̀ ìsàlẹ̀ kalẹ̀:

i. Ìwé ìdápadà owó-orí ti owó-àpawọlé ìjọba àpapọ̀ tí fọwọ́sí láìpẹ́;
ii. Àwọn fọ́ọ̀mù W-2 àti 1099 àìpẹ́;
iii. Àjákù ìwé ìsanwó àìpẹ́ (tàbí, tó bá nílò, ẹ̀dà ìwé gbólóhùn àìníṣẹ́, lẹ́tà ààbò ìgbàlódé, abbl.);
iv. Ìwé gbólóhùn láti ọ̀dọ̀ agbani-ṣiṣẹ́ tí a bá fọwọ́ sanwó; tàbí
v. Èyíkéyìí ìjẹ́rììsí míràn láti ọ̀dọ̀ ẹlòmíràn nípa Owó-àpawọlé ẹbí.

b. Ìwé ìbèrè kan fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a kò ní rí bí àìpéye èyí tó dá lórí ìkùnnà láti pèsè ìwé àkọsílẹ̀, tí aláìsàn náà bá ti pèsè ó kéré jù ọ̀kan nínú àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tó ṣàfihàn owó-àpawọlé fún Mọ̀lẹ́bí kọ̀ọ̀kan (pẹ̀lú aláìsàn náà) tí a kójọ sókè tó sì ti buwọ́lu ìwé ẹ̀rí náà, tàbí tó bá ṣẹlẹ̀ pé aláìsan náà kò le pèsè irú àwọn àkọsílẹ̀ náà, tí o ti buwọ́lu ìwé ẹ̀rí.

c. Àyàfi tó bá jẹ́ wípé Àmúyẹ Tí A Rò, olùbèrè náà gbọ́dọ̀ buwọ́lu ìwé ẹ̀rí ìbèrè. MHHS le gba ìpinnu rẹ padà tàbí ṣàtúnṣe rẹ̀ tí ẹ̀rí ọjọ́ iwájú bá ṣàfihàn pé olùbèrè náà pèsè àlàyé tó jẹ́ irọ́.

*Àfikún Ìwé Àkọsílẹ̀:* FAP ti MHHS kò nílò ìwé àkọsílẹ̀ ohun ìní tàbí ìnáwó. Ṣùgbọ́n Àwọn Olùbèrè le yàn láti pèsè àfikún ìwé àkọsílẹ̀ nípa àwọn ohun ìní, ìnáwó, owó-àpawọlé, àwọn gbèsè tókù tàbí àwọn àyídà míràn tí yóò ṣàfihàn ìnira owó láti ṣàtìlẹ́yìn fún ìbèrè kan fún Ìrànlọ́wọ́ Owó tó dọ́gba tàbí ju iye owó tó yẹ kí wọ́n san lọ sí FAP yìí.

9. *Àlàyé Irọ́ tàbí Ìṣinilọ́nà:* Tí a bá pinnu pé olubèrè kan ti pèsè àlàyé irọ́ tàbí èyí tó ṣìwá lọ́nà nípa agbára wọn láti sanwó ìtọ́jú ìlera, MHHS le sẹ́ àwọn ìbèrè ti olùbèrè lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí ti ọjọ́ iwájú. Tí a bá pèsè àlàyé irọ́ láìmọ̀, MHHS yóo dá ìpinnu rẹ̀ lórí àlàyé tí a túnṣe. Tí a bá ti fún ọ ní Ìrànlọ́wọ́ Owó tẹ́lẹ̀ lórí wípé aláìsàn náà ti pèsè àlàyé irọ́, MHHS le mú Ìrànlọ́wọ́ Owo tí a fifún un tẹ́lẹ̀ kúrò, bó ti wù kójẹ́ MHHS ni gbogbo ẹ̀tọ́ tó bá òfin mu láti wá ìsanwó láti ọ̀dọ̀ aláìsàn fún iyekíye tó yẹ fún sísan. Tí ìpèsè àlàyé irọ́ náà bá jẹ́ àṣìṣe, MHHS yóò dá ìpinnu rẹ padà èyí tí yóò sì dá lórí àlàyé ti a túnṣe.

**<u>ÀWỌN IBI ÌTỌ́KASÍ:</u>**

Òfin Ìfiránṣẹ́ Aláìsàn (EMTALA) àti Ìfaramọ́ Òfin Ìfiránṣẹ́ Ìlú Texas)
Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán Ìrànlọ́wọ́ Owó
Ìwé Ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó
Òfin Ìdíyelé àti Gbígbà

**<u>ÀWỌN ÀFIHÀN:</u>**

Àfihàn A - Ìṣirò Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè

Àfihàn B - Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀

*Tẹ̀síwájú lójú-ewé kejì.*

## Àfihàn A - Ìṣirò Iye Owó Tí A Máa Ǹ Bèrè

Iye Owó Tí A Máa Ǹ Bèrè dá lórí ìlànà ìpàrokò àti ìdíyelé tí MHHS ń lò fún owó Medicare fún-iṣẹ́ fún pàjáwìrì tàbí àwọn iṣẹ́ pàtàkì ti ìlera. Àpapọ̀ iye owó tí a gbàláyè láti Medicare ni a ó pín nípasẹ̀ àpapọ̀ owó ìdíyelé fún irú àwọn ìbèrè bẹ́ẹ̀, àti pé iye náà ni a ó yọkúrò láti inú 1 láti ṣírò ìdá ọgọ́rùún AGB náà.

**AGB % fún IP (Aláìsàn abẹ́lé) = Ìsanwó Medicare IP Tí A Gbàláyè / Àpapọ̀ Iye Owó**
**AGB % fún OP (Aláìsàn òde) = Ìsanwó Medicare OP Tí A Gbàláyè / Àpapọ̀ Iye Owó Medicare OP**

Ní ọdọdún, a ń ṣírò AGB lọ́tọ̀tọ̀ fún ilé-ìwòsàn kọ̀ọ̀kan, ṣùgbọ́n gbogbo ilé-ìwòsàn MHHS yóò ṣàmúlò ìdá ọgọ́rùún AGB tó kéré jù láàrín gbogbo ilé-ìwòsàn.

| Àwọn ohun àmúlò | Aláìsàn abẹ́lé | Aláìsàn òde |
|---|---|---|
| Memorial Hermann Greater Heights Hospital | 27% | 11% |
| Memorial Hermann – Texas Medical Center | 21% | 11% |
| Memorial Hermann Katy Hospital | 25% | 10% |
| Memorial Hermann Rehabilitation Hospital – Katy | 37% | 12% |
| Memorial Hermann Memorial City Medical Center | 25% | 13% |
| Memorial Hermann Northeast Hospital | 28% | 12% |
| Memorial Hermann Southeast Hospital | 27% | 11% |
| Memorial Hermann Southwest Hospital | 25% | 14% |
| Memorial Hermann Sugar Land Hospital | 25% | 11% |
| Memorial Hermann The Woodlands Medical Center | 27% | 12% |
| TIRR Memorial Hermann | 28% | 16% |
| University Place | 49% | N/A |

Ọdún Ìṣúná Owó 2021 (Oṣù Keèje 2020 - Oṣù Kẹẹ̀fà 2021) Iye Owó AGB Nìwọ̀nyí:

**Iye Owó Tí A Máa Ǹ Bèrè OP: 10%**
**Iye Owó Tí A Máa Ǹ Bèrè IP: 21%**

*Tẹ̀síwájú lójú-ewé kejì.*

**Àfihàn B - Ìtọ́ni Àìní Ìjọba**

Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó Àpawọlé Oṣọṣù Lápapọ̀ ni a tún ṣàyẹ̀wò nígbàtí a bá ṣàtúnṣe sí Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀. A ń mú tábìlì náà dójú ìwọ̀n lọ́dọọdún.
Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó Àpawọlé Oṣọṣù Lápapọ̀ túmọ̀ sí tábìlì owó àpawọlé ìsinsìnyí tí MHHS ń lò láti pinnu àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó lábẹ́ FAP yìí.

Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó Àpawọlé Ẹbí Oṣọṣù Lápapọ̀ dá lórí Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀ àti Tábìlì Àmúyẹ  Harris County Hospital District, bí a ti ń ṣàtúnṣe rẹ̀ láti ìgbàdégbà nípasẹ̀ àwọn aṣojú ìjọbá tó yẹ àti wípé tábìlì tí a ń sọ wà nílẹ̀ fún àtúnyẹ̀wò.

Jọ̀wọ́ wo tábìlì nísàlẹ̀:

| **Memorial Hermann Health System**<br>Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó Àpawọlé Lápapọ̀ | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀ (FPG) 2021<br>Àpapọ̀ owó àpawọlé ọdọọdún tàbí oṣọṣù láti le yẹ fún ìrànlọ́wọ́ owó tó dá lórí bí Ẹbí ti pọ̀ tó. | | | | | | |
| | 100% ti FPG | | 200% ti FPG | | 400% ti FPG | |
| Bí Ẹbí Ti Pọ̀ Tó | Owó Àpawọlé Ọdọọdún | Owó Àpawọlé Oṣọṣù | Owó Àpawọlé Ọdọọdún | Owó Àpawọlé Oṣọṣù | Owó Àpawọlé Ọdọọdún | Owó Àpawọlé Oṣọṣù |
| 1 | $12,880 | $1,073 | $25,760 | $2,147 | $51,520 | $4,293 |
| 2 | $17,420 | $1,452 | $34,840 | $2,903 | $69,680 | $5,807 |
| 3 | $21,960 | $1,830 | $43,920 | $3,660 | $87,840 | $7,320 |
| 4 | $26,500 | $2,208 | $53,000 | $4,417 | $106,000 | $8,833 |
| 5 | $31,040 | $2,587 | $62,080 | $5,173 | $124,160 | $10,347 |
| 6 | $35,580 | $2,965 | $71,160 | $5,930 | $142,320 | $11,860 |
| 7 | $40,120 | $3,343 | $80,240 | $6,687 | $160,480 | $13,373 |
| 8 | $44,660 | $3,722 | $89,320 | $7,443 | $178,640 | $14,887 |
| *Fún ẹbí/mọ̀lẹ́bí tó ní ju ènìyàn 8 lọ: ṣàfikún $4,540 fún ẹnìkọ̀ọ̀kan tí a ṣàfikún.* | | | | | | |